## (73) Suratul - Mussammilu

سُورَةُ المُزَّمِّلِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye,*
*Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Irẹ ẹniti o fi gọgọwu bori mọlẹ̀.

يَٰٓأَيُّهَا ٱلْمُزَّمِّلُ ١

**2.** Dide ni oru (ki o kirun) ayafi igbà diẹ.

قُمِ ٱلَّيْلَ إِلَّا قَلِيلًا ٢

**3.** Idaji rẹ̀, tabi ki o din ku diẹ ninu rẹ̀.

نِّصْفَهُۥٓ أَوِ ٱنقُصْ مِنْهُ قَلِيلًا ٣

**4.** Tabi ki o fi kun u, ki o si mã ka Al-Kurani letòletò.

أَوْ زِدْ عَلَيْهِ وَرَتِّلِ ٱلْقُرْءَانَ تَرْتِيلًا ٤

**5.** Dajudaju A o gbe ọ̀rọ̀ kan ti o wuwo le ọ lọwọ.

إِنَّا سَنُلْقِى عَلَيْكَ قَوْلًا ثَقِيلًا ٥

**6.** Dajudaju idide loru on ni ọna ti o lagabara ju, ti o si fin rin lẹ ju sinu ọkan ti o sin fi dara ju ni kika (ọrọ Ọlọhun).

إِنَّ نَاشِئَةَ ٱلَّيْلِ هِىَ أَشَدُّ وَطْـًٔا وَأَقْوَمُ قِيلًا ٦

**7.** Dajudaju iṣẹ ti o gba àkokò pupọ wa fun ọ ni ọsan.

إِنَّ لَكَ فِى ٱلنَّهَارِ سَبْحًا طَوِيلًا ٧

**8.** Atipe ki o mãṣe iranti orukọ Oluwa rẹ ki o maṣe nkan miran ju bẹ lọ ni ṣiṣe (gbe ara rẹ fun U patapata).

وَٱذْكُرِ ٱسْمَ رَبِّكَ وَتَبَتَّلْ إِلَيْهِ تَبْتِيلًا ٨

**9.** Oluwa ibuyọ õrun ati ti ibuwọ õrun, kò si ọlọhun miran lẹhin Rẹ̀, nitorina ki o mu U ni alafẹhinti.

رَّبُّ ٱلْمَشْرِقِ وَٱلْمَغْرِبِ لَآ إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ فَٱتَّخِذْهُ وَكِيلًا ٩

**10.** Atipe ki o fi ara da ohun ti nwọn sọ ki o si pẹ wọn silẹ̀ ni ipẹ̀silẹ ti ọmọluwabi.

وَٱصْبِرْ عَلَىٰ مَا يَقُولُونَ وَٱهْجُرْهُمْ هَجْرًا جَمِيلًا ١٠

وَذَرْنِي وَالْمُكَذِّبِينَ أُولِي النَّعْمَةِ وَمَهِّلْهُمْ قَلِيلًا ﴿١١﴾

**11.** Atipe ki o fi Mi silẹ̀ pẹlu awọn olupe nirọ, ti nwọn ni ọrọ, ki o lọra fun wọn fun igba diẹ.

إِنَّ لَدَيْنَا أَنكَالًا وَجَحِيمًا ﴿١٢﴾

**12.** Dajudaju ṣẹkẹṣẹkẹ̀ ti o wuwo wa lọdọ Wa ati ina jonijoni.

وَطَعَامًا ذَا غُصَّةٍ وَعَذَابًا أَلِيمًا ﴿١٣﴾

**13.** Ati onjẹ ti o npa ni lori (nfun enia lọrun) ati iyà ẹlẹta-elero.

يَوْمَ تَرْجُفُ الْأَرْضُ وَالْجِبَالُ وَكَانَتِ الْجِبَالُ
كَثِيبًا مَّهِيلًا ﴿١٤﴾

**14.** Ni ọjọ ti ilẹ̀ ati awọn oke nlanla ti nwọn o ma mi, awọn oke nlanla nwọn yio di yanrin ti a kojọ ti o ntuka.

إِنَّا أَرْسَلْنَا إِلَيْكُمْ رَسُولًا شَاهِدًا عَلَيْكُمْ كَمَا أَرْسَلْنَا
إِلَىٰ فِرْعَوْنَ رَسُولًا ﴿١٥﴾

**15.** Dajudaju Awa ti ran ojiṣẹ kan si nyin, ti o jẹ olujẹri le nyin lori, gẹgẹbi A ti ṣe ran ojiṣẹ kan si Firiaona.

فَعَصَىٰ فِرْعَوْنُ الرَّسُولَ فَأَخَذْنَاهُ أَخْذًا وَبِيلًا ﴿١٦﴾

**16.** Ṣugbọn Firiaona kọ ti ojiṣẹ nã, Awa wa ki i mọlẹ ni mimu ti o le.

فَكَيْفَ تَتَّقُونَ إِن كَفَرْتُمْ يَوْمًا يَجْعَلُ
الْوِلْدَانَ شِيبًا ﴿١٧﴾

**17.** Nigbati ẹnyin ṣe aigbagbọ bawo ni ẹnyin o ṣe paiya ọjọ kan ti o mu awọn ọmọ kẽkèke hu ewu?

السَّمَاءُ مُنفَطِرٌ بِهِ ۚ كَانَ وَعْدُهُ مَفْعُولًا ﴿١٨﴾

**18.** Yio mu sanma faya si meji. Alukawani Rẹ̀ nilati ṣẹ ni.

إِنَّ هَٰذِهِ تَذْكِرَةٌ ۖ فَمَن شَاءَ اتَّخَذَ إِلَىٰ رَبِّهِ
سَبِيلًا ﴿١٩﴾

**19.** Dajudaju eyi jẹ iṣinileti kan; ẹniti o ba fẹ ki o mu ọna ti yio gbe e de ọdọ Oluwa rẹ̀ pọn.

۞ إِنَّ رَبَّكَ يَعْلَمُ أَنَّكَ تَقُومُ أَدْنَىٰ مِن ثُلُثَيِ اللَّيْلِ وَنِصْفَهُ
وَثُلُثَهُ وَطَائِفَةٌ مِّنَ الَّذِينَ مَعَكَ ۚ وَاللَّهُ يُقَدِّرُ اللَّيْلَ

**20.** Dajudaju Oluwa rẹ mọ pe irẹ ma nfi ohun ti o kere ju meji idata oru duro (kirun), tabi idaji rẹ̀, tabi idamẹta rẹ̀ ati apakan ninu awọn ti o wà pẹlu rẹ. Atipe

Ọlọhun nfi idiwọn si oru ati ọsan. O si mọ pe ẹ kò ni le ṣọ ọ, nitorina O ṣiju anu wo nyin, nitorina ẹ mã ke iwọn ba (ti agbara yin ba ka) diẹ ninu Al-Kurani. O si mọ pe alaini alafia yio wà ninu nyin, atipe awọn ẹlomiran (yio wa ninu nyin) ti nwọn fẹ rin ilẹ̀ (Ọlọhun) lọ ti nwọn yio lọ wa ninu õre-ajulọ Ọlọhun, ati awọn ẹlomiran (yio wà) ti nwọn yio ma jà ni oju ọna ti Ọlọhun. Nitorina ẹ mã ke eyiti o rọrun (fun yin) ninu rẹ̀. Ki ẹ si mã gbe irun duro ki ẹ si mã yan saka, ẹ mã fi si ọdọ Ọlọhun ipin ti o dara (ninu ọrọ nyin lati na si oju ọna ti Ọlọhun). Nitoripe ohun yiowu ti ẹ ba ti ṣiwaju fun ẹmi nyin ni nkan daradara, ẹ o ba a lọdọ Ọlọhun, pe on lo dara ju, lo si tobi ju ni ẹsan. Atipe ki ẹ tọrọ idariji lọdọ Ọlọhun. Dajudaju Ọlọhun ni Alaforiji, Onikẹ.

وَالنَّهَارَ عَلِمَ أَن لَّن تُحْصُوهُ فَتَابَ عَلَيْكُمْ فَاقْرَءُوا
مَا تَيَسَّرَ مِنَ الْقُرْآنِ عَلِمَ أَن سَيَكُونُ مِنكُم مَّرْضَىٰ
وَآخَرُونَ يَضْرِبُونَ فِي الْأَرْضِ يَبْتَغُونَ مِن فَضْلِ
اللَّهِ وَآخَرُونَ يُقَاتِلُونَ فِي سَبِيلِ اللَّهِ فَاقْرَءُوا
مَا تَيَسَّرَ مِنْهُ وَأَقِيمُوا الصَّلَاةَ وَآتُوا الزَّكَاةَ
وَأَقْرِضُوا اللَّهَ قَرْضًا حَسَنًا وَمَا تُقَدِّمُوا لِأَنفُسِكُم
مِّنْ خَيْرٍ تَجِدُوهُ عِندَ اللَّهِ هُوَ خَيْرًا وَأَعْظَمَ أَجْرًا
وَاسْتَغْفِرُوا اللَّهَ إِنَّ اللَّهَ غَفُورٌ رَّحِيمٌ ٢٠

## *(74) Suratul - Muddassiru*

## سُورَةُ المُدَّثِّر

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

**1.** Irẹ ti o da aṣọ bori mọlẹ̀.

يَا أَيُّهَا الْمُدَّثِّرُ ١

**2.** Dide ki o mã ṣe kilọkilọ.

قُمْ فَأَنذِرْ ٢

**3.** Ki o si mã ṣe agbega fun Oluwa rẹ.

وَرَبَّكَ فَكَبِّرْ ٣

**4.** Ki o si ṣe awọn aṣọ rẹ ni mimọ.

وَثِيَابَكَ فَطَهِّرْ ٤